**ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU**

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**ÈTÒ ÌPÀDÉ AGBÁRA GBỌ́DỌ̀ PÀRỌ̀ ỌWỌ́**

**OGUN LÒDÌ SÍ ÌDÈ OLUBI**

**OṢÙ KÁRÙN, ỌDÚN 2023**

Ìwé Mímọ́ kíkà: Jòhánnù 9

Ìjẹ́wọ́: Ìsáíàh 54:17

## ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN TÍ Ó L'ÁGBÁRA

1. Ọlọ́run, dìde, kí Ó sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìṣọ́ji, bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, jẹ́ kí agbára àláfíà àti itẹ̀síwájú, ṣíji bo orílẹ̀-èdè yìí, ní orúkọ Jésù.
4. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fún wa ní àwọn olórí tó bẹ̀rù Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
5. Ìwọ ilé ìfowópamọ́ sí sátánì, tú olubi mi sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
6. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, tú olubi mi sílẹ̀ kúrò nínú ilẹ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo àsopọ̀ olubi ní ìlú tí a ti bími, kílò n dúró ṣe e? Kú, ní orúkọ Jésù.
8. Mo já ìdodo mi kúrò lọ́wọ́ ilé ọmọ ìkùnà, ní orúkọ Jésù.
9. Gbogbo agbára nínú omi, tú olubi mi sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
10. Mo gé dànù, gbogbo odò búburú tó n ṣàn látọ́dọ̀ àwọn òbí mi sínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
11. Mo gé dànù, gbogbo ràbọ̀-ràbọ̀ àwọn ohun òkùnkùn tí wọ́n sin papọ̀ pẹ̀lú olubi mi, tó lòdì sí ayànmọ́ mi, ní orúkọ Jésù.
12. Gbogbo àhámọ́ àwọn ọdẹ ìràwọ̀, ti àwọn olùpa ìràwọ̀ àti ti àwọn awòràwọ̀, fọ́ nípa iná, ní orúkọ Jésù.

13. Gbogbo irinṣẹ́ ìyàbàrà tó lòdì sí ayànmọ́ mi, ṣègbé nípa iná, ní orúkọ Jésù.
14. Ìwọ ọkùnrin alágbára olubi, tú ayé mi sílẹ̀ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
15. Bàbá Olúwa, bí mo ṣe má a kígbe "Ẹ̀jẹ̀ Jésù" nígbà méje, jẹ́ kí gbogbo àdàlù nínú ẹ̀jẹ̀ mi di fífọ̀ jáde, ní orúkọ Jésù.
16. Gbogbo igi búburú tó bá olubi mi dá májẹ̀mú búburú, fọ́, kí o sì gbiná, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo odù àjẹ́, tó n dúkokò mọ́ ayànmọ́ mi nípa ṣẹ̀ olubi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
18. Gbogbo ìwà ìkà tí wọ́n ṣe sí olubi mi, tapadà lónì, ní orúkọ Jésù.
19. Gbogbo iṣẹ́ ìjìnlẹ̀ òkùnkùn lórí olubi mi, gba ifàtu nípa iná Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
20. Gbogbo àhámọ́ ìtọpinpin olubi, fọ́ báyì, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo ibùkún tí mo pàdánù nípa ṣẹ̀ ìṣe àjẹ́ olubi, mo gbà ọ́ padà, ní orúkọ Jésù.
22. Mo fọ́ gbogbo agbára ẹ̀rọ ìdarí, tó n ṣiṣẹ́ àyídáyidà olubi lòdì sí mi, ní orúkọ Jésù.
23. Mo gba ohun gbogbo tí wọ́n jí lọ́wọ́ mi nípa ṣẹ̀ àyídáyidà olubi, ní orúkọ Jésù.
24. Gbogbo àjọ àjẹ́, tú olubi mi sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
25. Ìwọ ilé ọmọ ilẹ̀, tó n lo olubi mi gẹ́gẹ́ bí ṣẹkẹ́ṣẹkẹ̀, fọ́, kí o sì túmisílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
26. Gbogbo májẹ̀mú tó n bẹ lárìn olubi mi àti ibojì, fọ́, ní orúkọ Jésù.
27. Mo ge dànù, gbogbo àgbébọ̀ sátánì tí wọ́n fi sọwọ́ sínú ayànmọ́ mi nípa ṣẹ̀ olubi, ní orúkọ Jésù.
28. Gbogbo àyídáyidà olubi ìrandíran lórí ayé mi, gba ifàgilé, ní orúkọ Jésù.
29. Gbogbo igi àjẹ́ tó de olubi mi, fọ́, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
30. Gbogbo ẹyẹ àjẹ́ tí wọ́n yàn lòdì sí olubi mi, kú, ní orúkọ Jésù.
31. Gbogbo agbára tó n lo olubi mi láti pe ẹ̀mí mi, mo fọ́ agbára rẹ, ní orúkọ Jésù.

32. Gbogbo àhámọ́ àyídáyidà olubi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
33. Gbogbo ẹnubodè àìsàn, tó ṣí sílẹ̀ fún ayé mi nípa ṣẹ̀ olubi, dípa nípa iná, ní orúkọ Jésù.
34. Mo ge dànù, gbogbo àdàlù ìrandíran, tí wọ́n fi sọwọ́ sínú ayànmọ́ mi nípa ṣẹ̀ olubi, ní orúkọ Jésù.
35. Gbogbo ẹnu ọ̀nà òṣì, tó ṣí sílẹ̀ fún ayé mi nípa ṣẹ̀ olubi, dípa nípa iná, ní orúkọ Jésù.
36. Gbogbo iṣìnkú àjẹ́ lórí olubi mi, gba ìfagilé nípa iná, ní orúkọ Jésù.
37. Ilé ìfowópamọ́ sí omi, tú olubi mi sílẹ̀, ní orúkọ Jésù.
38. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, gba olubi mi lọ́wọ́ àwọn ègún àjẹ́, ní orúkọ Jésù.
39. Mo tú ìwọ́ mi sílẹ̀ kúrò nínú ilé ọmọ òṣì, ní orúkọ Jésù.
40. Gbogbo ọkọ/aya t'ẹ̀mí, tó sọpọ̀ mọ́ olubi mi, kú, ní orúkọ Jésù.